IBADAN UNIVE...
16 SEP 1974
THE ED FOR IMOLE OWURO
7/9/74
IBADAN

Kongi Nap WK 4
3, 10, 15.
ASIKO Bks Wk 4
16 28, 42.
ROSS BKS Wk 4
4 & 8

# Imọlẹ Owuro

UNITY NPS
For 3 sure draws in Wk 7 try to see The Manager Unity Pools House, E4/226, Gbelekalẹ Ibadan.
See him with ₦5 before 2 p. m. on Saturday.
7 10 35, 44

Ẹsin Ọrọ Wa: "IMỌLẸ DE! OKUNKUN PARADA"

Independent Paper VOL. XIII No 655 SATURDAY SEPTEMBER 7 – FRIDAY SEPTEMBER 13, 1974 5K. (KỌBỌ MARUN

# IJỌBA KILỌ FUN AWỌN ABỌRIṢA ORO NI ISẸYIN



ỌGAGUN OLUWỌLE ROTIMI
Gomina Ologun Iwọ-Oorun.

IJỌBA Ologun Ipinlẹ Iwọ-Oorun ti kilọ gidi-gidi fun awọn abọriṣa oro ni ilu Isẹyin pe ki nwọn lọọ ṣe wọọ ni akoko ọdun oro ti nw n nṣe lọwọ yi ki nwọn ma baa lufin Ọba.

Ninu ọrọ rẹ fun awọn oleri na ni ilu Isẹyin ni ọsẹ ti o kọja, Ajẹlẹ Ọran Lọbalẹba ati ti Ijọba Ibilẹ ni Ipinlẹ Iwọ-Oorun Alufaa J. A. Akinyẹmi sọ pe, ọdọ-ọdun ni ẹsun aṣeju ati aṣeṣa lati ọwọ awọn oloro na maa nde eti Ijọba.

Siwaju si i, Alufaa na sọ pe ọdọọdun ẹwẹ ni Ijọba pẹlu awọn agbofinro maa nṣeto ọdun na fun awọn oloro na ki rogbodiyan ma baa ṣe bẹsilẹ ni akoko ọdun na, ṣugbọn ti nwọn kii tẹle e

Nitorina, Alufaa Akinyẹmi sọ pe Ijọba ko le la oju rẹ silẹ ki rogbodiyan fi bẹsilẹ ni ilu nitori "ṣiṣe ẹsin ibilẹ" Alufaa na sọ pe ẹsin yowu ti ko ba ka alaafia ilu kun yẹ ni ohun ti awọn olusin rẹ yẹ ki o tun ero pa lelori

Ni ọjọ ti ọdun oro ku ọla ti yio bẹrẹ ni Alufa Akinyẹmi ba awọn olusin naa sọrọ.

O ni Ijọba ti paṣẹ fun awọn agbofinro lati gbaradi lati gbe ofin ro ni akoko ọdun oro na.

Nigbana ni Alufaa Akinyẹmi rọ Asẹyin Isẹyin Ọba Raji Adebọwale, awọn Ijoye rẹ ati awọn Aworo oro lati tẹle ilana alaafia ti awọn agbofinro lasilẹ fun ti ọdun na.

Ṣugbọn o kilọ gidi-gidi pe ẹnikẹni ti o ba rekọja ilana na, Ijọba yio fi igi imu rẹ fọn fere.

IDI ABAJỌ

Onirohin wa ran wa leti pe ohun ti o fa
(Woju ewe kẹfa)

## Kini ọdun to yi?

ILE—IṢẸ OGO OLUWA KIITAN TRADING STORES, ti gbe awo rẹkọọdu nla titun ti gbajumọ oṣere nni FATAYI OLOWONYỌ ati awọn oṣere rẹ ṣẹṣẹ ṣe jade, eyiti nọmba rẹ jẹ OKLP 17, VOL. 3.



FATAYI OLOWONYỌ
(Onijita Aramọnda)

Awo na pabambari, o le gongo. A gbọ ma le lọ ni orin inu awo titun na. Ti ilu ti nwọn lu ninu rẹ ni ki a sọ ni tabi Jita aramọnda ti Olowonyọ ta sinu rẹ ? "Ko nun l'odo" ni awo rẹkọọdu yi, "ti o ba dele a di oyinmọmọ".

Bakanna ni awo rẹkọdu OKLP 11 ati OKLP 13, VOL. 1 - 2, ti ẹ ti mbeere rẹ ti wa bayi fun tita.

Koṣeemani ni awọn awo wọnyi fun igbadun abẹle nigbagbogbo.

Ẹ le ri wọn ra ni ile - itaja rẹkọọdu l'adugbo nyin tabi l'ọdọ Olupinja:
OGO - OLUWA KIITAN
TRADING STORES,
51, Railway Line
Odi - Olowo, Muṣin
Tel. 46252
Tabi ni Ẹka wọnyi:
* 119, Herbert Macaulay St. Ebute - Mẹtta.
* 2, Badejọ Street. Agege Lagos State.

AKEDE ONA IYE

# AKOKO NA NIYI:

# E dide ni otun iwa (1)

BI ẹnyin ti nka iwaasu mi lati igba - de - igba ko ba gbagbe, ninu iwe irohin yi kanna ni a ti nfi asọtẹlẹ Ọrọ Ọlọrun han ẹnyin enia aiye pe, igba na de ti idajọ yio bẹrẹ lati ile Ọlọrun wa I Peteru 4, 17.

Bi a ba si wo o, a o ri i pe ọpọ Ijọ Ọlọrun l'oni ni o kun fun iwa Ikunsinu, eyi ti a le sọ pe o maa nṣẹlẹ lati ọdọ Olori tabi ẹgbẹ ninu Ijọ. A ti sọrọ pupọ nipa eyi ṣaaju.

Bakanna ni a ti kesi awọn enia aiye ninu iwe yi kanna pe, ọpọ Woli eke ni yio dide, ti nwọn yio maa lọ agbara eṣu ati bẹẹbẹẹ lọ. Mattieu 24, 4.

Melo ni a o ka ninu Alalupayida (Magicians) ti nwọn ti sọ araa wọn di Woli l'ode oni ? Melo l'a o ka ninu ologun ti o nfi araa rẹ pe Woli ? Melo ni a o si ka ninu abokusọrọ ti nwọn ti sọ araa wọn di Woli pẹlu ?

Ko si ohun miran ti nwọn nfi orukọ Oluwa kojọ ti o ju dukia aiye asan yi lọ. Ọrọ Ọlọrun ti sọ tẹlẹ nipa wọn pe, nipa eso wọn ni a o fi mọ wọn.

Nigbati awọn enia ba de ọdọ wọn, nwọn a maa pin owo fun wọn. Nwọn a da gbese owo nla bọ alaisan miran l'ọrun. Nipa bayi, aisan ti mbẹ l'ara rẹ ni ekinni aisan ai ri owo nla ti Woli mbeere si ni ekeji ! Ẹkẹta ni pe, alaisan na ko tun nii ri alaafia !!

Ṣugbọn Ọrọ Mimọ Ọlọrun ti kilọ fun ọ ṣaaju pe "Nipa eso wọn ni a o fi mọ wọn"; o ku si ọwọ ẹnikẹni ti o ba fẹ otitọ lati maṣe sunmọ wọn.

Nitori ki olukuluku enia le mọ ọna ti yio rin ni ọrọ Ọlọrun ṣe sọ fun wa pe ki a tete maa kigbe ki awọn enia le gbọ ki nwọn si fi ọna iwabuburu silẹ nitoripe Oluwa sọ pe, ẹnikẹni ki yio jare niwaju oun.

Bakanna ni o jẹ pe ọpọ awọn ẹni ibi okunkun aiye ni nwọn maa nhuwa ikọkọ ti awọn enia kii mọ itumọ rẹ. Ṣugbọn ninu ilẹ ni ewe ati egbo ti nwọn maa nlo ti njade wa.

Nkan wọnyi ni nwọn maa nlo fun iṣẹ ibi, bẹẹni inu ilẹ ko dun si i, tobẹẹ ti ilẹ fi binu pe awọn ọmọ oun (ewe ati egbo) ko nii jiṣẹ mọ fun awọn ti nwọn nlo ọmọ oun ni kọkọ ti nwọn si npe wọn ni enia rere.

Njẹ gbogbo agbara okunkun ti ọmọ araiye nlo kọ ni o ndi mimọ ni gbangba bayi? Njẹ aṣiri ohunkohun bo mọ? Oluwa ko ha nfi aṣiri iṣẹ okunkun olukuluku enia han ni gbangba bi?

Njẹ nigbati iwọ mọ idarijin titi lai, ṣugbọn o wa ninu ẹbi ainipẹkun: Mark 3,24.

Lati ọjọ pipẹ wa ni awọn enia iparun ti npẹgan Jesu Kristi, lati igbana wa ni egun asọtẹlẹ si ti wa l'ori wọn titi di oni yi.

Njẹ ko ha yẹ ki awa enia ti ikilọ ikẹhin de ba yi ronu ki a ṣe ifẹ Ọlọrun wa lati oni lọ ki o too pẹju? Ọlọrun wa ko fẹ iku ẹlẹṣẹ bikoṣe ki o fi ẹṣẹ rẹ silẹ ki o si ye, idi si niyi ti Ọlọrun fi nranṣẹ si wa fun ironupiwada.

Ṣugbọn mo fẹ ki o ye ẹnyin enia aiye yi pe, iwaasu yi ki iṣe iwaasu ti a fi nwa ojurere l'ọdọ oniwe irohin tabi, jẹ iwaasu oṣelu. Rara o, iwaasu yi duro

LATI ỌWỌ WOLI S. I. OWOẸYẸ

pe Ọlọrun nṣe eyi, kini ero rẹ si Ẹni na ti O da ọ; ti o mọ ohun gbogbo ti O si lee ṣe ohun gbogbo; Ani ẸNI na ti ilẹ ati oke wa ni ikawọ Rẹ?

Nitoripe, awa ni igbẹhin aiye deba, gbogbo aiye si ti ngbọ ikilọ igbẹhin bayi; nipa eyi ti a o fi maa da enia rere mọ si buburu. Iwọ ki yio tẹle ikilọ Oluwa bi ki o ma baa jẹbi l'ọjọ ikẹhin?

Gbogbo iwaasu ti mo nṣe wọnyi jẹ asọtẹlẹ. Nitorina, ẹ ranti pe, asọtẹlẹ kan ko ti ipa ifẹ enia wa ri: Ṣugbọn awọn enia nsọrọ lati ọdọ Ọlọrun bi a ti ndari wọn lati ọwọ ẸMI-MIMỌ wa: II Peteru 1,21.

Ọrọ Ọlọrun si ti sọ fun wa gbangba pe, Ẹni ti o ba sọrọ odi si ẸMI-MIMỌ kii ri gẹgẹ bi Angẹli Oluwa ti o nwa awọn enia ti o sọnu kiri lati gba wọn la ni.

Nitorina bi o ba duro iwọ yio ni ipin ninu ire na. Gbogbo asọtẹlẹ ti Oluwa ti nsọ lati ọjọ yi wa ti bẹrẹ si i ṣẹ bayi, Oluwa si ti gba Ijọba, O wa nwa enia ti yio dari aiye.

Oluwa ti wa mbeere lowọ ẹnikọọkan bayi pe, Njẹ iwọ yio duro? Ibeere yi dojukọ awa Ojiṣẹ Ọlọrun gbogbo ati Oludari ipo nlanla aiye gbogbo paapaa julọ awọn ti nwọn ni aṣẹ l'ẹnu lati ṣe atunṣe ọna ẹsin Igbagbọ lai yẹsẹ.

Lẹhin na, ki iwọ ati emi dide l'ọtun lati maa bẹ Oluwa gẹgẹ bi Hesikiah ti ṣe ti Oluwa fi fi kun ọjọ aiye rẹ.

Nitorina ẹnyin ẹni okunkun aiye, ẹ maa bọ ninu IMỌLẸ. Toripe bi ọkunrin ṣe maa mba obinrin lopọ ninu okunkun ti ikun alaboyun si maa nfi han ni gbangba ti ọmọ si maa njade sinu IMỌLẸ, bẹẹ gẹgẹ ni aṣiri ohun ikọkọ kankan ki yio bo ninu aiye mọ.

ADURA

Oluwa rere, gba wa Amin.



WOLI S. I. OWOẸYẸ
Oniwaasu naa.


## IwE ORO OLORUN

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkọọkan, mo ti ṣeto lati maa fi apapọ iwe na ṣọwọ si nyin ni aadọta Kobo (50k) pere.

Awon Iwe na ni:
1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ?
4. Ẹ JỌWỌ ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa. Fi owo ranṣẹ si:

Woli S. I. Owoẹye,
Box 1206,
Ibadan.

## ARA NFAAJO




"PIRI l'olongo nji a ki i ba okunrun ẹiyẹ l'ori itẹ" Fun agbara akọtun lojoojumọ, maa lo MAGNATONE TỌNIKI.

Beere ni ile itaja adugbo rẹ tabi ni:

BASOTO PHARMACY
63, IDUMAGBO AVENUE
LAGOS.


# 15&23

# Ajihinrere J.K. Solomon kolu awọn Eleri Jehofa

GBAJUMỌ Ajihinrere kanni Naijiria Ajihinrere J. K. Solomon ti lodi si ohun ti o pe ni "ẹkọ odi" ti awọn Ẹlẹri Jehofa fi nkọ awọn enia kaakiri aiye, eyi ti o pe ni "iṣina".

Nibi ipade isọji ọlọjọ mẹsan ti o ṣe ni ilu Ilọrin, eyi ti o bẹrẹ ni ọjọ kerindinlogun si ẹkerinlelogun oṣu kejọ ọdun yi ni o ti sọrọ na.

Lẹhin ti Ajihinrere Solomon ti ṣe oniruuru itọkasi ninu Bibeli lati fi gbe ọrọ rẹ lẹsẹ, o wi bayi: "Dipo ti awọn enia na ki ba fi maa lọọ waasu fun awọn ti ko tii gbagbọ, awọn Onigbagbọ ni nwọn maa nwa kiri ti nwọn yio si maa tumọ Bibeli lodilodi".

Bakanna ni Ajihinrere Solomon bu ẹnu atẹ lu gbogbo awọn oniwaasu ti nwọn ti sọ Ijọ wọn di oku nipa ai fi onjẹ iye ati otitọ bọ wọn.

O kilọ fun wọn lati yara bila kuro ninu ibinu Oluwa ti o mbọ bi nwọn ba kuna lati ṣe ifẹ Ọlọrun ti o jẹ pe ipo aiye yi ni nwọn nwa fun araa wọn.

## IṢẸ IWOSAN

Ni akoko isọji na. ọpọlọpọ iṣẹ iyanu ni Oluwa ti ọwọ Ajihinrere Solomon ṣe. Koko ohun ti o fi ṣe isọji na ni "KRISTI NI IDAHUN".

Ara awọn iṣẹ iyanu ti Oluwa ṣe ni ti odi ti nsọrọ, aditi ti ngbọran, ati awọn obinrin ti nwọn ri imularada ninu oniruuru aisan wọn.

Eyi ti o ṣe iyanu ju ni ti ọdọmọkunrin kan ti o wa lati Oturkpo ni Ipinlẹ Benue- Plateau, ẹni ti ọwọ ọtun rẹ ti rọ lati iwọn ọdun mẹrin sẹhin ti ko si ṣee gbe ohunkohun. Bi o ba fẹẹ wọ ẹwu, nṣe ni nwọn maa mba a wọ ọ.

Ṣugbọn ninu isọji ti ọjọ 'Bọ ti iṣe 22/8/74 ni o ri iwosan gba, o si fi ọwọ na kọwe l'oju gbogbo enia.

## IWOSAN ẸMI

Yatọ si iṣẹ iwosan ti ara ti Oluwa ṣe nibi isọji na, o tun ṣe ti ẹmi pẹlu nitoripe ọpọlọpọ enia ni o jẹwọ JESU KRISTI gẹgẹ bi Olugbala wọn.

Ni ipari isọji na ni apapọ, Ajihinrere Solomon ṣipaya pe idasilẹ ile iwe ẹkọ ihinrere (School of Evangelism), eyi ti o sọ pe ọpọlọpọ ti gba iwe iforukọsilẹ lati kẹkọ nibẹ yio waiye laipẹ yi.

O ni oun ko tii mọ ibi ti ile iwe na yio duro si; "ṣugbọn nigbati eto ba pari l'ori rẹ, gbogbo awọn ti o fi orukọ silẹ ni yio gbọ".

## Mufutau komo

ọjọ kẹẹdọgbọn INu kejọ ọdun yi ni Ọgbẹni Mufutau ati Aya re Iyafin Sidikatu Agbeke fi jijẹ mimu tẹ awọn alabaṣẹyẹ l'ọrun nibi inawo Ikomọjade ti ọmọkunrin kan ti Ọlọrun fi ta wọn l'ọrẹ.

Ni agbo ile Idiagbọn Ibadan ni ayẹyẹ ikomọjade na ti waiye Saidi Babatude Mufutau ni wọn sọ ọmọ na.

Diẹ lara awọn enia ti o wa sibi ikomọ na ni Amusa Ajani, Yinusa Ajagbe, Lekan Ọladeji, Tijani, Ọlawuwo, Tiamiyu, Latifu Fatai, Silifatu, Limọta Ikẹpe, Amudatu ati Munirata.


## ANFANI FUN O

Kinni iṣoro rẹ? Kini ẹdun ọkan re? Kini o nru o loju? iwọ ha nlalakala bi? Tabi ohunkohun nru ọ loju ninu Bibeli bi?

Ọfẹ ni a o fi gbogbo nkan wọnyi ye ọ. Fi apo iwe ti o lẹ Stamp 5k mọ ara rẹ pẹlu address rẹ sinu iwe ti o ba kọ si mi.

Ero mi ni lati fi ẹbun ti a fun mi ran araiye lọwọ.

Kọwe si :
Woli S. I. Owoẹye
N6/763A Kabiawu Street,
Mọkọla Ibadan.

ASỌTẸLẸ

"Ibi ni yio pa enia buburu ati awọn ti o korira olododo yio jẹbi" Orin Dafidi 34, 2



## Apprentice Wanted

LEARN to become a successful printer. Learn on mordern marchine with modern technique.

Parents, don't waste the time of your fresh Primary six & mordern III school leavers send them to learn the art of modern Printing, Marchine operating, and Book - binding from us. Apply personally today.

The Works Manager,
(Imọlẹ Owurọ)
N4/496B Yemetu Aladọrin,
Ibadan.


## Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ

10,983 James Arẹmu, Ogbomọṣọ
10,984 Timothy Adeniji, Abẹokuta
10,985 Bisiriyu Agboọla, Ikirun
10,986 Babatunde Owokoniran, Kutọnu
10,987 Ezekiel Aiyegbọyin, Ogbomọṣọ
10,988 Samuel Ajayi, Gbọngan
10,989 R. A Ajijọlakewu, Ogbomọṣọ
10,990 Akinwale Yẹkini Ọfa
10,991 Mufutau Adegbokiki, Abẹokuta
10,992 Lawal Oṣuọlale, Ogbomọṣọ
10,993 Lawal Adedokun, Ogbomọṣọ
10,994 Joseph Ajiboye, Ogbomọṣọ

FUN IGBEGA EDE ATI AṢA YORUBA
DI
**Omo Egbe Imole Owuro**
(Iwe idi ọmọ Ẹgbẹ)

Orukọ rẹ ____________________

Adirẹsi rẹ: ____________________

Ọmọ ilu ti o jẹ ____________________

Jawe yi ki o si poosu rẹ si
DOKUN AJADI
(Akọwe Ẹgbẹ)
P. M. B. 5230, Ibadan


## Ifilo Pataki

1975 OGBOMỌṢỌ ILU AKỌNI 1975

ALIMANAKI ATI KALẸNDA

Yio jade laipẹ; ki awọn onibara ati awọn aṣoju wa gbogbo jakejado ilẹ Naijiria fi eti si awọn ifilọ wọnyi :

1, Awọn ohun elo ti a nlo fun titẹ iwe jade ti wọngogo ni asiko yi ti o fi jẹ wipe 25k ni Alimanaki ẹyọ kan ati 15k Kalẹnda ẹyọ kan yio jade lati ọdọ wa si ọdọ awọn aṣoju wa gbogbo ti ẹ o si maa ta ni 30k fun awọn onibaara wa gbogbo.

2. A nfẹ ki awọn asoju wa gbogbo fi idaji owo iyekiye dọsinni ti nwọn ba fẹ ransẹ si wa lati isinsinyi lọ.

3. A nfẹ aṣoju lati ilu wọnyi: Sokoto, Maiduguri, Nguru, Zaria, Funtua, Bida ati awọn ilu miran ni Oke Ọya ti a ko ba ti ni aṣoju.

Ẹ tete fi owo nyin ransẹ si Ile Ẹrọ itẹwe wa;

OJUBANIRẸ PRINTING WORKS
Masifa Postal Agency
Ita--popo, Ogbomọṣọ

# Arẹsa-Adu ṣe isin idupe Oye



ỌBA OYEDEPO ẸMIOLU
Arẹsa-Adu Irẹsa Adu

NI ọjọ kẹẹdọgbọn oṣu kẹjọ ọdun yi ni Arẹsa-Adu titun ilu Irẹsa-Adu Ọba Jacob Oyedepo Ọladipọ Ẹmiolu Keji pẹlu ọpọlọpọ awọn enia ba a jọ sin nile ijọsin Ijọ Onitẹbọmi kinni ni ilu Irẹsa-Adu.

L'ara awọn ti o ba a lọ ni awọn Ọba Ijoye, oniṣowo awọn ẹnibi- ẹni ati awọn eniabi-enia pẹlu awọn sanmọri ilu ati orekelẹwa obinrin.

Ninu iwasu rẹ l'ọjọ na, Ojiṣẹ Ọlọrun Ijọ Onitẹbọmi ni Irẹsa-Adu Oniwasu S.O. Ojo gba awọn Ọba ati awọn ijoye ilẹ wa niyanju lati maa fi Ọlọrun ti ṣise Ọba awọn Ọba, ẸNI tii fi Ọba jẹ, ṣe ibikinni ninu iṣẹ iṣakoso wọn l'ori itẹ. O tun rọ wọn lati ni ibẹru Ọlọrun ki nwọn si pa ofin Rẹ mọ ki iṣakoso wọn le yọri si rere.

O pe ori ọrọ rẹ eyi ti o mu lati inu Bibeli Mimọ, iwe Oniwasu ori kejila ẹsẹ kẹtala (12:13- bayi "Bẹru Ọlọrun ki o si pa ofin Rẹ mọ.

O tunṣe itọkasi oriṣiriṣi ninu Bibeli Mimọ lati gbe iwasu rẹ lẹsẹ. Oniwasu Ojo ran awọn Ọba leti pẹlu lati maa ṣe afarawe Ọba Solomon ti o beere fun ọgbọn ati oye ti o fi ṣe akoso ati idajọ ododo lori awon enia rẹ.

Diẹ t'aye wa fun l'ara awọn enia nlanla ọjọ na ni Oloye A. O., Oloye Ọlọkọṣe ilu Oko Onijado, Oloye Ojo Akan Mọlete, Alagba Jimọ Adeniyi Eko ila, Amos Arubiewe, Emmanuel Ọladipọ, Garuba Buraimọ Lagbẹdu Aworawọ, Gbensoye Ọlalẹyẹ Oloye S. O. Ogundipẹ ati bẹẹbẹẹ lọ.

# Ọko Ọba sa Onise Ọba l'ese

OṢIṢE ile ifiweranṣẹ (Postal Agent kan Muhamọdu Iswata ẹni ọdun mejilelogun ti ibi iṣẹ ifiweranṣẹ Postal Agency. Pategi ni Ipinlẹ Kwara foju ba ile ẹjọ ibilẹ Onipo kinni ilu Ilọrin laipẹ yi fun ẹsin afọwọra.

Afẹsunkanni sọ fun ile ẹjọ pe, iwadi awọn Ọlọpa fihan pe ọdaran na gba awọn iwe-owo (Postal Orders) ti iye owo rẹ jẹ Naira marundinlọgọjọ (N155) lọwọ oniruuru enia pẹlu laarin oṣu karun si oṣu kẹjọ ọdun yi, pẹlu alaye pe oun yio ba wọn sọ ọ di owo. Awọn afẹsunkanni sọ pe ṣugbọn dipo dida owo wọnyi pada fun wọn, ọdaran na da owo na si apo araa rẹ

Adajọ ile ẹjọ na Alhaji S. Nababa, ko gbọ ọrọ l'enu ọdaran na, ṣugbọn o gba iduro rẹ l'ori igba Naira (N200.) Ẹjọ na yio tẹsiwaju ni ọjọ kẹrinla oṣu kẹsan.

Omo onibulu tuntun alagbara otun a ma fo aso mo julo...o si han gbangba



new super active



# Moto pa Adota enia

IROHIN ibanujẹ kan ti o gbọdekan ni aarin ọsẹ yi ni ijamba mọto kan ti o ṣẹlẹ ni ọna Eko ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹta oṣu kẹsan ọdun yi nibiti aadọta enia ti ku lẹsẹkẹsẹ ninu ọkọ bii mẹta ti o forigbari, ti ọpọlọpọ si wa ni ẹsẹ kan aiye ẹsẹ kan ọrun.

Mọto mẹta ni ijamba na ṣẹlẹ si. Awọn mọto na ni ti Ijọba Ipinlẹ Ado—Ibinni kan, ọkọ awọn ọmọ ogun oju omi kan, ati ọkọ akero kan.

Ẹnikẹni ko le sọ iye enia ti o ku lẹsẹkẹsẹ nitoripe ọpọ enia ni mọto na rẹ bẹtẹbẹtẹ, ṣugbọn awọn alakiyesi kan l'o sọ pe o kere tan, oku ni lati to ogoji, ati pe o le ni aadọta enia ti o wa ni ẹsẹ kan aiye ẹsẹ kan ọrun bayi nile iwosan Ijẹbu—Ode.

Bakanna ni ijamba mọto tun ṣẹlẹ ni apa ibomirau ni Iwọ-Oorun, ara rẹ ni ti ọna Ọyọ.

IWE IGBAẸLODE DARA PUPỌ

1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 10k
2. Kurani esu marun Yoruba 55k Esu kan (25k)
3. Yasin ni Yoruba (15k)
4. Zabura ati itumọ (55k)
5. Zabura Yoruba (40k)
6. Iwe Aiye Akamara (50k)
7. Iwe Eniaṣoro (50k) Adedẹwẹ (35k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (N3); Kekere (75k)
9. Iwe ala ni nla (N1.50)
10. Kekere (30k)
11. Iwe Oogun iwosan (N1.5) Kekere (45k)
12. Itan Anabi ati Yisa (55k)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (25k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a Odo—ye Adeọyọ Rd, P. O. Box 3365, Mapo—Ibadan.



(2) Alufa Igbaẹlode, Mọsalaṣi Idi-Iṣin St, Isalẹ Koto P. O. Box 17 Ilọrin.

# Oloro Iseyin

(Lati oju ewe kini)

eyi ni jijade ti awọn oloro kii fẹ ki awọn obinrin jade gba ọjọ meje gbako tọsantoru, eyi ti ko dun mọ awọn Ijọ Onigbagbọ ati Oni male ninu.

Nitori eyi ni awọn agbofinro fi lọwọ si adehun ti o waiye larin awọn Aworo oro ni apa kan ati awọn Onigbagbọ pelu Onimọle ni apakeji.

Adehun na sọ pe, oro ko gbọdọ jade lati agogo mefa owurọ di agogo mẹjọ alẹ ki awọn obinrin baa le raye maa jade. Adehun yi ni Alufaa Akinyemi nkesi wọn lati tẹle ni akoko ọdun na ki alaafia le wa.

# Pools

## Jovial Nap

Week 6

Nap 2, 23. 33

perm 2, 5, 8, 23. 33

If no 33 draws these will be 3 sure draws in week 7

33xxbk

## ojo Adisa Nap

(3&2) Banka marun wa ti o nwa lẹẹmẹta l'ọdọdun o tun mbọ ni wk 8 pẹlu wk 10 ati wk 12, fi N9 ranṣẹ fun tirẹ. Fun mẹtamẹta l'ọsẹ, fi N5 ranṣẹ si:

Ojo Adisa,
N4/273 Adeọyọ Oje Rd; Ibadan
26*?

# OLORIRE O ! OLORIRE O !!

AWA ẸGBẸ ONIṢOWO

## WESTERN NIGERIAN TECHNICAL COMPANY LIMITED

TI A JẸ ONIṢOWO ẸRỌ TI O DARA
NI O NKESI ẸNYIN ONIṢOWO GẸDU
PE, A TI GBE ORIRE TIYIN NA DE.
BI Ẹ BA NFẸ KI IṢẸ NYIN MAA
GBERU SI I,
TI Ẹ NFẸ KI OWO NLA—NLA MAA WỌLE
TI Ẹ SI FẸ WA NI YỌTỌMI
NI GBOGBO IGBA,
ẸRỌ WA ATATA ALAGBARA
NLA KAN TI NJẸ




## SOLO CHAIN SAW

**(With 30" Blade) N315.00**

Ti a fi nge gẹdu ni orişişiri
Ni o yẹ fun ọ lati ra.
Bi o ba ti ni ẹrọ na
Ma foiya mọ, bukata rẹ ti biiya
Owo ẹrọ na ko pọ. N315 · 00 pere ni:
Ki iṣe iru ẹrọ yi nikan ni a ni
Orişirişi fun oniruuru iṣẹ ni o mbẹ pẹlu.

Bakanna ni a si ni ẹrọ ilọta "BECO"
Ẹ sa tete maa bọ pẹlu Imọlẹ Owurọ kan ti a polowo ẹrọ yi si ninu si:

**Western Nigerian Technical Company Limited,**

P. M. B. 5148; PHONE 22361/2
DUGBẸ ONIMATIRẸSI, IBADAN.

Pinted and Published by The Peoples Star Press Ltd, N4/496B Yemetu Aladọrin P. M. B. 5230 Ibadan Olotu (Editor) Lawuyi Ogunnira